1

Ọ̀nà tí a ṣe lè ṣọ gbogbo nǹkan tí a máa ń ṣe ni ojojúmọ́ di nǹkan ẹ̀kọ́

Ọ̀rọ̀ sísọ, ọ̀rọ̀ gbígbọ́, ìwé kíkà, eré ṣíṣe

Ẹ̀kọ́ kíkọ́ máa ń bẹ̀rẹ̀ ní gbogbo nǹkan tí a máa ń se

3

Àwọn ọmọdé máa ń tètè bẹ̀rẹ̀ sí ní kọ́ ẹ̀kọ́ lẹ́hìn tí wọ́n bá tí bí wọn

4

lẹ́hìn tí wọ́n bá tí bí ọmọ, ọmọ náà a bẹ̀rẹ̀ sí ní mọ àwọn ẹbí rẹ, àyíká rẹ, àti nǹkan tí ó lè ṣe fún ara rẹ̀. Bí ọmọdé yìí bá ṣe ń dàgbà si ni gbogbo ìrírí rẹ̀ ṣe máa tún bọ̀ jẹ́ kí òye àti ìmọ̀ràn rẹ máa pọ̀si

5

**Nígbàtí ọmọ náà bá wọ ilé ìwe alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, á lè lo gbogbo ẹ̀kọ́ tí ó kọ́. Tísà ilé ìwé rẹ̀ máa fi oríṣiríṣi ìwe hàán, á jẹ́ kí ó, ya àwòrán, pa àlọ́, sọ ìtàn àti ṣe ọ̀rẹ́ tuntun.**

Tísà ilé ìwe alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ yìí máà kọ bí ọmọdé yìí ṣe n ṣe ní kíláàsì sílẹ̀. Á mójútó àwọn nǹkan tí ó máà jẹ́ kí ọmọdé yìí se dáà dáà ní ilé ìwe. Tí ó bá ní lo láti mọ nǹkan tí óyẹ kí ó mọ̀, tísà yìí a wá àwọn nǹkan tí ó máà ràán lọ́wọ́.

Gẹ́gẹ́ bí òbí, o lè kọ́ ọmọ rẹ kí ó tó bẹ̀rẹ̀ ilé ìwe kí ọmọdé yìí le se dáà dáà ní ilé ìwe. ìwé yìí ní oríṣiríṣi nǹkan tí o lè lò ni ojojúmọ́ kí ọmọ rẹ le mọ nǹkan méje tí ó ṣe pàtàkì fun ọmọ rẹ ní ilé ìwe alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀.

- Ìdàgbà ara wa ní àyíká wa
- Èdè àti ìwé kíkà
- Ìdàgbà ọgbọ́n wa ní
  Ìṣirò
  Sáyẹ́ǹsì
  Ẹ̀kọ́ nípa aiyé tí à ń gbé
  Eré áàtì
- Ìdàgbà ara wa

Bẹ̀rẹ̀ lónìí pẹ̀lu àwọn iṣẹ́ ṣíse wọ̀n yìí.

6

Èdè sísọ àti ìwé kíkà

Èdè sísọ àti ìwé kíkà pẹ̀lú gbogbo nǹkan tí ó máà kọ́ ọmọ rẹ ní ìwé kíkà, ìwé kíkọ, àti bí wọ́n ṣe lè ṣe àpèjúwèé nǹkan tí ó wà ní orí wọn pẹ̀lú èdè sísọ.

7

**O lè lò àwọn iṣẹ́ ṣíse wọ̀n yìí láti fi kọ́ ọmọ rẹ ní èdè sísọ àti ìwé kíkà**

- Lẹ́hin tí o bá ti bí ọmọ rẹ, máà bá sọ̀rọ̀ ní ojojúmọ́. Pàápàá nígbàtí o bá wà ní kékeré, ọmọ rẹ á máà kọ́ ohùn èdè.
- Dá ọmọ rẹ lóhùn tí ó bá sọ ọ̀rọ̀ kí ọ̀rọ̀. ọmọ náà fẹ́ kọ́ bí wọ́n ṣe ń sọ̀rọ̀, ó sì fẹ íràn lọ́wọ́ rẹ pẹ̀lú ìgbéraga.

- Ṣeré pẹ̀lú ọ̀rọ̀..àwọn ọ̀rọ̀ tí ó bára mu àti ọ̀rọ̀ ti kò ní ìtumọ̀.
- Ka ìwé pẹ̀lu ọmọ rẹ ní ojojúmọ́. Àwọn ọmọ kékeré náà máà n gbádùn àkókò ìwé kíkà àti ọ̀rọ̀ tuntun tí o bá ṣe àpèjúwe pẹ̀lú àwòrán.
- Bi ọmọ rẹ ní ìbéèrè nígbàtí ẹ bá jọ ń kàwé, bèrè nípa àwọn àwòrán àtí nǹkan tí ó máà ṣẹlẹ̀.
- Fún ọmọ rẹ ní àwọn nǹkan ìlò fun ìwé kíkọ, aàlọ̀ọ́, àmì bí ó ti lẹ̀ jẹ́ wí pé kò tíì mọ nǹkan kan kọ.
- Nígbàtí ìwọ àti ọmọ rẹ bá wà pẹ̀lú àwọn ènìyàn púpọ̀, fún ọmọ rẹ ní àyè láti sọ̀rọ̀ fún ara rẹ̀ kà kà kí o báà dáhùn tàbí kà kà kí o sọ fun pé kí ó tètè dáhùn.

8

Ìdàgbà ara wa ní àyíká wa

Ìdàgbà ara wa ní àyíká wa èyí jẹ́ àwọn nǹkan tí ọmọdé ní lò láti le jẹ kí ó lè fi ara balẹ, sọ̀rọ̀ láàrín ẹgbẹ́ rẹ̀, àti bí ó ṣé lè hùwà ní ta nígbà ti ó bá jáde sí inú aiyé.  Pẹ̀lú bí nǹkan ṣé wà pẹ̀lú òbí àti àwọn ènìyàn.

9

**Àwọn òbí lè ran ọmọ wọn lọ́wọ́ láti kọ́ ẹ̀kò tí wọ́n ní lò láti lè hùwà ní awùjọ wa.**

- Ran ọmọ rẹ lọ́wọ́ tí óbá ń sọkún.  Pẹ̀lú èyí  ọmọ rẹ á mọ̀ wípé o fẹ́ràn rẹ̀.
- Lo àsìkò yìí látí jẹ́ kí ọmọ rẹ mọ̀ wípé o fẹ́ràn rẹ̀.  Fa ọmọ rẹ mọ́ra kí osì rọra báà sọ̀rọ̀. Èyí a jẹ́ kí wọ́n lè kọ́ wọn láti lè tètè di ọ̀rẹ́ pẹ̀lú àwọn ènìyàn.
- Jẹ́ kí ọmọ rẹ kọ́ oríṣiríṣi nǹkan tuntun fún ara rẹ kí o sì yìín ní gbogbo ìgbà...fún àpẹrẹ ní ọjọ́ kiní tí ó bá kọ́kọ́ rìn, jẹun fún ara rẹ̀, kọ́kọ́ sọ ọ̀rọ̀
- Fi ise ti omo re se si ori firigi ati ori ara ogiri ni inu ile re ki o ba le mo wipe inu re dun pupo.
- Fi ona han omo re bi o se le mo iru iwa ti o ye ki o fi han ni gbati inu re ko ba dun.  Ko omo re bi o se le mo nigbati inu awon elomiran dun tabi ko dun.
- Kọ́ ọmọ rẹ bí o ṣe lè tọ́ju ara rẹ nígbati ó ba ni ìṣòro.  Kọ́ ọmọ rẹ wipe o gbọ́dọ̀ bèrè ibéèrè nígbati ó ba ni ìṣòro kàkà ki o gbìyànjú lati ṣe nǹkan ti órò wipe ọ́ tọ́

10

Ìronú pẹ̀lu ìṣirò

Ìdí ti oye ki a mo isiro ni wipe ki a baa le mo nomba, wọn nǹkan, pátáànù àti ṣéèpù.  Awọn ọmọ nilo lati mọ awọn nǹkan wọn yii lati le se iṣiro.

11

**Àwọn obí lé ran ọmọ wọn lọ́wọ́ láti kọ́ bí wọ́n ṣe le ronu iṣiro**

- Ka oríṣiríṣi nǹkan ní gbàti ó bá ń ṣe nǹkan kí nǹkan pẹ̀lu ọmo rẹ ni ojojúmọ́. Ka ìka ẹsẹ̀ ọmọ rẹ nígbàtí o bá ń wẹ̀ẹ́.  Ka bọ́tíìnì aṣọ rẹ̀ nígbàti o bá ń ba múra.  Ka oye ẹsẹ̀ ti ẹ bá gbé nígbàtí ẹ bá ń rìn.
- Fi àwọn nǹkan tí o tóbi tàbí tí ó kéré ju ara wọn han ọmọ rẹ. Fún àpẹrẹ ìwé, nǹkan ìṣeré, bàtà ati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Yan oríṣiríṣi nǹkan gẹ́gẹ́ bi àwọ̀ kọ́lọ̀ wọn tàbi bí wọn ṣe tóbi sí.  Fún àpẹrẹ sítọ́kíìnì aláwọ búlúù tabi gbogbo aṣọ ọmọ rẹ.
- Se àlàyé pátáànì , bèrè lọ́wọ́ ọmọ rẹ pé pátáànì bílọ̀ọ̀kì , àwòrán tí ó wà ni orí aṣọ tàbí ìlẹ̀kẹ̀ wo ni ó máà tẹle.
- Lo ọ̀rọ̀ bi jù lọ àti kéré jù ati awọn ọ̀rọ̀ tí ó fi ipò han, fun àpẹrẹ, abẹ́, lórí, lóke.

- Fi ṣéèpù oríṣiríṣi han ọmọ rẹ pẹ̀lu gbogbo nnkan, fún àpẹrẹ, ṣéèpù pálí oúnjẹ àárọ̀, séèpù abọ́.
- Fí kọ́ọ̀bù àti ṣíbí tí a máà fi ń wọn oúnjẹ han ọmọ rẹ.  wọn bí ọmọ rè ṣe ga tó pẹ̀lú téèpù tàbí igi.
- Sọ̀rọ̀ pẹ̀lú ọmọ rẹ nípa nǹkan tí ẹ máà ṣe ní ojojúmọ́.  Lẹ́hìn oúnjẹ ọ̀sán, amáà lọ sí páàkì lẹ́hìn náà a máà lọ sí ọjà.

12

Ìronú sáyẹ́ǹsì

ìronú sáyẹ́ǹsì pẹ̀lú ìmọ̀ nípa àyíká wa àti kíkọ́ nípa bí a ṣe máà bèrè ìbéèrè nítorípé o ṣe pàtàkì.  Ó yẹ kí a fun àwọn ọmọdé ní àyè láti mọ nípa àyíkà wọn pẹlu, ìrírí wọn, àlàyé wọn, ìbéèrè wọn àtí ìdáhun fun ara wọn.

13

**O lè ran ọmọ rẹ lọ́wọ́ láti ṣe àwọn nǹkan yìí kí ó báà  lè rónú pẹ̀lú sáyẹ́ǹsì**

- Rìn pẹ̀lú ọmọ rẹ níta kí o sì fetí sí orí ṣiríṣi ohùn, òórùn àti nǹkan tí ẹ bá rí.
- Jẹ́ kí ọmọ rẹ seré pẹ̀lú iyẹ̀pẹ̀ àti omi..
- Sọ̀rọ̀ nípa wẹ́dà, jẹ́ kí ọmọ rẹ sọ nǹkan tí ó máà ṣẹ lẹ̀ pẹ̀lú wẹ́dà òjò tàbí oòrùn.
- Jẹ́ kí ọmọ rẹ seré pẹ̀lú ẹranko inú ilé, ẹyẹ kí ó sì sọ́rọ̀ nipa ìwà wọn.
- Kọ́ ọmọ rẹ nípa àwọn èso àti ẹranko tí ó fẹ́ ní ìmọ̀ nípa.
- Wá oríṣiríṣi nǹkan ní ìta tí ọmọ rẹ le yẹ̀wò bíi òkuta, ewé, fúláwà ati èso.
- Fi gíláàsì tí o lè mú nǹkan tóbi, bìnókúláàsì àti rúlà yẹ nǹkan oríṣiríṣi wò.
- Jẹ́ kí ọmọ rẹ wo bí àwọn nǹkan oríṣiríṣi ṣe máà n tètè lọ tabi rọra rìn, jẹ́ kí ó sọ àwọn nǹkan tí ó máà lè dúró lorí omi tabi nǹkan tí ó máà rì sí abẹ́ omi, jẹ́ kí ó mọ̀ wípé omi ni ó máà ń di bílọ́ọ̀kì áísì.

14

Ẹ̀kọ́ nípa aiyé tí à ń gbé

Èyí jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ìmọ̀ràn àwọn ọmọdé nípa aiyé tí ó yí wọn ká tí wọ́n sì ń gbé.  Nígbàyí ni wọ́n máà mọ arawọn gẹ́gẹ́ bî arawọn, wọ́n máà mọ wípé àwọn ènìyàn yàtọ̀ àti wípé wọ́n máà fẹ́ mọ̀ nípa àwọn oríṣiríṣi ìwà tí ó wà ni àgbáiyé yìí tí ó yí wọn ká.

15

**You can help your child develop social studies skills.**

- Sọ̀rọ̀ nípa ìyàtọ àtí nǹkan tí o rí bákan náà láàrin ẹbí rẹ àti ẹbí èlòmíràn.  Sọ̀rọ̀ ní pa nǹkan bî oye ọmọ, bí àwọn ọmọ náà ṣe ga sí, ọmọ ọdún tí wọ́n jẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Sọ̀rọ̀ nípa iṣẹ́ tí gbogbo ènìyàn tí ó wà ní ẹbí rẹ ń ṣe.
- Ran ọmọ rè lọ́wọ́ látì ṣe bî pé wọ́n jẹ́ àwọn ènìyàn tí wọ́n mọ̀ ní àdúgbò yín, fún àpẹrẹ, tísà, dọ́kítà àti ọ̀ṣìṣẹ́ ọjà.
- Lọ sí oriṣiriṣi ojà tí o wa ni àdúgbò rẹ, sọrọ nípa oríṣiríṣi nǹkan tí wọ́n máà ń ṣe, sọrọ nípa ilé ọjà títà, ilé bàtà títà, ilé oògùn títà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Dá òfin sí lẹ̀ nípa ìgbà tí ó yẹ kí wọ́n lọ sùn tàbí bí wọ́n ṣe lè pìín iṣẹ́ ilé láàrín wọn.
- Ìwọ àti ọmọ rẹ, ẹ jìjọ ṣa ìdọ̀tí tí ó wà ní àdúgbò yín kí o sì sọ fun ní ìdì tí ó ṣe pàtàkì kí ẹ jíjọ jẹ́ kí àdúgbò yín mọ́ láì sí ìdọ̀tí.
- Ìwọ àti ọmọ rẹ, ẹ jìjọ lọ́ sí ibi oriṣiriṣi bî ilé ìkàwé, mùsíọ̀mù ati ilé ìdárayá páàkì.

16

Àwọn erè áàtì

Àwọn erè áàtì pẹ̀lú bí àwọn ọmọdé se lè wà ní eré ijó, eré dìrámà, àwòrán yíyà àti orin kíkọ. Pìpẹ̀lú àwọn ọmọdé ní irú àwọn eré iṣẹ́ yìí ṣe pàtàkì nítorípé wọ́n máà mọ̀ wípé gbogbo nǹkan tí wọ́n ń ṣe tí wọ́n sì ń rí se pàtàkì.

17

O lè ran ọmọ rẹ lọ́wọ́ nípa ìmọ̀ áàti pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ ṣíṣe wọ̀n yìí.

- Kọrin kí osì pàtẹ́wọ́ pẹ̀lú ọmọ rẹ
- Nígbàtí o bá ń kọrin pẹ̀lú rédíyò jẹ́ kí ọmọ rẹ jó àti kọrin pẹ̀lú rẹ.
- Pèse nǹkan bîi ṣíbí, pọ́ọ̀ti, àti ike agolo tí ọmọ rẹ fi lè lùlù nígbàtí ẹ bá ń gbọ́ orin.
- Pèsè oríṣiríṣi nǹkan tí ọmọ rẹ fi lè ya àwòrán.  Jẹ́ kí ó sọ fún ọ nípa nǹkan tí ó yà.
- Ran ọmọ rẹ  lọ́wọ́ láti sọ ìtàn tí ó fẹ́ràn jùlọ di eré dírá
- Mú ọmọ rẹ lọ wo eré bîi orin kíkọ, eré dírámà àti eré áàtì ọ̀fẹ́ tí ó wà ní àdúdò yín, ilé ìsìn, ní ìta gbangba àti ní ọjà.

18

Ìdàgbà àti ìtọ́jú ara wa

Ìdàgbà àti ìtọ́jú ara wa pẹ̀lú bí aṣe lè kọ̀ọ́ bí a ṣe ń di nǹkan ìkọ̀wé mú, eré sísá àti ìfò fífò, àti bí a ṣe lè fi pẹ̀lẹ́ pẹ̀lẹ́ ṣeré láì ṣe ara wa lé ṣe.

19

Ó lè ran ọmọ rẹ lọ́wọ́ pẹ̀lú ìdàgbà ara rẹ̀

- Fi bọ́ọ̀lù ṣeré pẹ̀lú ọmọ rẹọ́ bọ́ọ̀lù gbígbá, mímú, jíjù..
- Pèse orísiríṣi nǹkan tí ọmọ rẹ lè fi ṣeré bîi bílọ̀ọ̀kì, lẹ́gò àti pọsúùlù tí ó sòro.
- Pèse nǹkan ìlò áàtì tí ọmọ rẹ lè gèé, lẹ̀, kùn àti yà.
- Fún ọmọ rẹ ní àsìkò tí ó ní lò láti ṣe àwọn nǹkan kékèkèé fún àpẹrẹ, àsìkò láti fọ ọwọ́ rẹ tàbí láti wọ kóòtì àti bàtà rẹ fún ara rẹ̀.
- Jẹ́ kí ọmọ rẹ ràn ẹ lọ́wọ́ pẹ̀lú iṣẹ́ ilé, fún àpẹrẹ, tábìlì títẹ́, mímú búrẹ́ẹ̀dì jáde fún oúnjẹ ọ̀sán, tàbí ṣíṣa aṣọ rẹ̀ tí ó ti dọ̀tí.
- Kọ́ ọmọ ilé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ rẹ bí a ṣe ń so okùn bàtà tàbí okùn fún pálíi ẹ̀bùn.
- Jẹ oúnjẹ tí ó dára tí ó bá ni lára mu pẹ̀lú ọmọ rẹ kí o sì sọ̀rọ̀ nípa àwọn oúnjẹ tí kó dára àti èyí tí ó dára.
- Kọ́ ọmọ rẹ bí a ṣe ń fọ ọwọ́ àti eyín wa.

20

...àti ní pàápàá jùlọ, yin ọmọ rẹ nígbàtí ó bí gbìyànjú.  ìrànlọ́wọ́ rẹ máà fún ní àyà láti dán nǹkan wò, láti bèrè ìbéèrè, láti fẹ́ràn àti láti kọ́ nǹkan kí nǹkan.

**Countdown to Kindergarten** jẹ́ ìdàgbà tí ó wà káàkiri ìpínlẹ̀, ó sì pẹ̀lú oríṣiríṣi ilé ìwé, ilé ìkàwé àti àwọn tií ó fẹ mójú tó àwọn ọmọ Maryland láti kọ́ ẹ̀kọ́ ilé àti ìrírí tí ó dára kí wọ́n baà lè múra láti ṣe dáadáa ní ilé ìwé.

Tí o bá fẹ́ rí àwọn ìwé ẹ̀kọ́ ìkàwé láti àwọn ẹgbẹ́ yìí, lọ sí wẹ́ẹ̀bù **www.countdownMD.org** tàbí pe nọ́mbà ọ̀fẹ́ yìí **1-866-752-1614.** Wẹ́ẹ̀bù yìí ní nǹkan ìmọ̀ nípa bi aṣe le mọ̀ bóyá ọmọ ti setán láti lọ ilé iwé, bí a ṣe lè yan ẹ̀kọ́ tí ó dára, bí a ṣe lè wọn bí ọmọ ṣe ń ṣe ní ilé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀,  àti lóri iṣẹ́ ṣíṣe tí àwọn òbí le ṣe láti ran ọmọ wọn lọ̀wọ̀.

Tí o bá ní ìbéèrè nípa bí o ṣe lè kọ́ ọmọ rẹ ní ẹ̀kọ́ ìbéèrè, pe nọ́mbà 1-800-535-0182 láti sọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn ará Maryland Infants and Toddlers Program àti Preschool Program ní Maryland State Department of Education.

Countdown to Kindergarten gba owó lọ́wọ́ọ M&T Bank, Harry and Jeanette Weinberg Foundation, Governor's Office for Children, Youth and Families, Constellation Energy, ati National Governors Association. Àwọn òṣìṣẹ́ wá láti Maryland Committee for Children. Countdown To Kindergarten: Learning Begins at Birth kí Countdown to Kindergarten: Boston fún ìràn lọ́wọ́ wọn àti fún ìlò àmì lógò wọn

Countdown to Kindergarten: Learning Begins at Birth
Maryland's Early Childhood Public Engagement Campaign
608 Water Street
Baltimore, Maryland 21202

www.countdownMD.org

© 2004 Maryland Committee for Children
Illustrations: © 2004 Bonnie Matthews